UTC
DEPARTMENT STORE
THE
FINEST SHOP
FOR
MEN'S WEAR

ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

## Asayan Oro

Ewurẹ wo alapata, bi ki o ku. Awodi wo Igbin kọrọ, Kini ẹiyẹ oko yio fi Igbin ṣe ? Ori l'o nise ẹda l'a yanmọ.

VOL. XI No. 652. LAGOS, SATURDAY, DECEMBER 5. — DECEMBER 11, 1959. KỌBỌ MEJI (2d)

# Awon Osise Ile Ina Da Ise Sile Jake-jado Ile Nigeria.

Irohin gbojikan kakiri ilu Eko wipe awọn oṣiṣẹ ile ina lẹntiriki ti Ijọra ko ni ṣiṣẹ wọn deede, nwọn o si ma ṣe imẹlẹ lẹnu iṣẹ, nişişe bayi, ina ti a ntan si igboro ko ni tan lati ọjọ Alamisi.

Nigbati awọn atọkun ibiṣẹ na ṣe akiyesi pe, asiko lati tan ina to, ti ina ko si tan, Ọgbẹni J. Bullock sare lọ sibi iṣẹ o gba iṣẹ lọwọ wọn, o si tan ina. Ohun ti a gbọ wipe oda họwu họwu yi silẹ ni wipe awọn oṣiṣẹ mbere ẹkunwo (10 per cent).

Ọgbẹni A.E. Wyatt sọ wipe, bi nwọn ko ba wa sibi iṣẹ, iṣẹ yio ma ṣe niṣo dedee. Nitoripe awọn Igbimọ inu ile iṣẹ ti ṣe adehun fun awọn oṣiṣẹ pe awọn yio ṣe ayẹwo ati ṣe ekunwo wọn, şugbọn ki nwọn ṣe suru diẹ, ki Oluwadi ẹkunwo awọn oṣiṣẹ ṣe iwadi wọn tan.

### ADEHUN LORI OHUN IJA DIDANWO

AMERIKA. Awọn ilu alagbara mejila lo ṣe adehun papọ wipe, ẹnikẹni ti o ba fẹ dan awọn ohun ija ogun wo, ki nwọn maṣe danwo ni agbegbe ibiti a gbe le ri enia, şugbọn ki nwọn ma lọ dan awọn ohun ija bẹ wo ni Okun Antactic nibiti o jẹ pe ko si enia.

Ninu awọn to ṣe adehun yi, Ijọba ilẹ Amerika wa nibẹ, Ijọba Gẹsi wa nibẹ, Ijọba Rọsia papaa wa nibẹ. Ki imọ yi to jọ, o to iwọn ọsẹ meje ti nwọn fi sọrọ na ki o to bọsi.

(E D) Eyi ni abayori ọrọ ti Faranse sọ wipe bi Rọsia, Gẹsi ati Amerika ba dawọ atom Bomb ti won duro, on ko ni yin ẹtu oloro ti on wi ninu Sahara mọ.

No 186

## Government Notice

### Banking Ordinance, 1958.

It is notified for general information that Section 6 of the Banking Ordinance, 1958 which came into operation on 1st October, 1959, provides, inter alia, that save with the consent of the Minister of Finance for the Federation, no person other than a licensed bank shall use or continue to use the word "bank" or any of its derivatives either in English or in any other language, in the description or title under which such person is carrying on business in Nigeria.

The section also provides that any person who acts in contravention of its provisions shall be liable to a fine of fifty pounds for every day during which the offence continues.

## New Freight Rates To Ibadan.

YOU MAY NOW SEND YOUR GOODS BY FREIGHT TRAIN TO IBADAN FROM APAPA QUAY, APAPA LOCAL STATION AND LAGOS TERMINUS AT THE FOLLOWING SPECIALLY CHEAP RATES:

| | RATE PER TON |
|---|---|
| CEMENT ... — | 15/- |
| IRON SHEETS — | 20/- |
| ALL OTHER GOOD (Above Class 4 of the Railway Classification) | 22/ |

THERE ARE NO WEIGHT LIMITATIONS

The NIGERIAN RAILWAY CORPORATION will carry all your Loads however Large or Small

SEE HOW THESE NEW RATES COMPARE WITH THE OLD RATES :-

| COMMODITY | RATE PER TON TO IBADAN From Apapa, Lagos & Iganmu | |
|---|---|---|
| | OLD RATE | NEW RATE |
| Sugar | 38s | 22s |
| Beer, Ale and Stout | 38s | 22s |
| Piecegoods: | | |
| Manufactured | 55s | 22s |
| Unmanufactured | 42s | 22s |
| Petrol | 57s | 22s |
| Hardware ) Groceries ) Confectionery ) | 42s | 22s |
| Timber | 29s | 22s |
| Cement | 23s | 15s |
| Iron Sheets | 29s | 20s |
| All other traffic above Class 4. | 23s to 63s | 22s |

ELETI-OFE DARABA

## Omo Ile Nigeria Gba Oye O. B. E



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni omo ile Nigeria kan ti o nṣe aṣoju fun agbegbe Ila-Orun, Ọgbeni Felix Ihenacho ti o ngbe ilu London ni Alaiyeluwa Ọba Gesi fi Oye nla O. B. E. da lọla nigbati o nse ojo ibi rẹ.

Nigbati o dele, o nfi oye na han iyawo re gegebi a ti nwo ninu aworan yi. Ọkọ Ọba Prince Phillip lo fi oye na mọ Commissioner F. Ihenacho laya. A gbọ pe enia mọkandinigba ni nwọn fi oye da lọla lọjọ na.

## OBINRIN KAN BIMO ELENMỌ NI ADEỌYỌ

Gbogbo ẹnia nrọ girigiri lọ si ile Alaisan ni Adeọyọ lati lọ fi oju ri iru ọmọ elenmọ kan ti obinrin rodo-rodo kan bi, eyiti o di okiki ti gbogbo ilu fi nrọ girigiri lati lọ fi oju ri ọmọ elenmọ na.

Bawo ni ọmọ na ti ri gan-n ti gbogbo enia fi nrọ lọ wo o bayi? Ohun abami ti o mbẹ lara ọmọ na ni wipe, ko ni oju rara bẹni ko ni eti awọn elo miran sọ pe iho kekere kan lo mbẹ niwaju ori ti o fi nmi, ati pe ni agbọn isalẹ ni ẹnu rẹ wa.

Ni gẹrẹ ti nwọn bi ọmọ na silẹ tan lo bẹrẹ si mi.

Lẹsẹkanna, irohin titan kalẹ wipe obinrin daradara kan bi ọmọ abami kan sile alabiyamọ ni Adeọyọ nilu Ibadan.

## ỌMỌ ỌDUN MẸWA NSAN OWO ORI NI BORNU

ZINNA A gbo irohin wipe nilẹ Bornu ni agbegbe ilẹ Hausa, awon omokunrin ti o ba ti dagba to omo odun mẹwa ni lati bere si san owo ori. Awon ara ilu na kebosi wa ba egbe awon oselu pe ki nwon ba won se na ti awon

Wo yoku loju ewe kẹjọ

## FEDERAL ELECTION 1959.

No 185

Many people have lost their registration cards. This does not mean that they cannot vote, but it does mean that they may have to wait while the Presiding Officer deals with those voters who have brought their cards.

They are therefore advised to try to find out before Polling Day what their registration number was. They can discover this by consulting the Register of Electors for their locality. They can find out where a copy of the Register is by enquiring at the nearest Government office or by asking the local agent or organiser of a political party.

The Electoral Commission would be grateful if local party organisations would help any member of the public who seeks their information. It has already been suggested to Electoral Officers that they should do so.

Those who manage to discover their registration number should make a note of it on a slip of paper. This will NOT entitle them to priority, but when their turn comes it will prevent time from being wasted in tracing their names on the Register, which is not in alphabetical order.

**R. E. Wraith**
Chairman, Electoral Commission

Plushes, Velvet Velveteens, Damask

& Building Materials

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

63, Massey Street, (Faji Market)

LAGOS NIGERIA

The House where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed



## ǪWǪ ǪLǪPA TĘ ǪDARAN TI O TI SALǪ

ABA. Ǫkunrin awamǫto kan ti orukǫ rę nję Udofia Umǫ ni awǫn ǫlǫpa ramu ti nwǫn și nfę ba șe ęjǫ ni ǫdun 1956, șugbǫn o sa mǫ awǫn ǫlǫpa lǫwǫ latigba na ni nwǫn si ti nwa a ti nwǫn ko ri.

Ni ǫdun ni, ni ǫwǫ tęę ni ilu Aba ni gbati o wa gba iwe titun lati ma fi wa mǫto ibę ni awǫn ǫlǫpa ti ki i mǫlę, ti nwǫn si mulǫ si kotu wipe ęni atijǫ ti anwa kiri ni yi, ti o wa ara rę wa ba wa yi.

Ęsun rę ni wipe, nwǫn mu ni ǫdun 1956, nigbana akoko iwe așę rę ti pari, ko gba omiran o si nwa mǫto kakiri pęlu rę, fere mǫto rę ko ndun daradara, sibę, o nlǫ bę, nomba iwaju ati ti ęhin rę ti parę tan, sibę o nlǫ bę, o si tun sa kuro lǫwǫ ǫlǫpa, ki ǫwǫ to wa tę ni Aba.

Adajǫ wadi ǫrǫ na siwa sęhin o ri pe dęręba na jębi ęsun nwǫnyi, o ni ki o lǫ san ǫgbǫn Pǫnun tabi ki o lǫ si ęwǫn ǫșu męta. Ko si gbǫdǫ wa mǫto fun ǫșu męjidilogun.

Nwǫn sęgbimǫ wipe ki nwǫn fi ętu pamǫ si National Bank ti Ilaro, nwǫn wa lǫ ba okunrin olojo kan lati fajo si ibę. Ęniti nwǫn ran lo pe olojo l'o lo rohin fun olopa.

## ĘBGĘ ALAKUKǪ LO KO IJǪGBǪN WA SILĘ YORUBA

ǪYǪ. Nigbati Oloye Akintǫla nsǫrǫ nilu Ǫyǫ. O wipe ki awǫn oyinbo to de ilę Yoruba nigbati ogun ba bę silę larin awǫn ilu meji ni akoko na ni awǫn janduku ęnia ma nko ara jǫ (Thug). Awǫn Yoruba ko npe ni janduku. Sunmǫmi ni nwǫn npe e, awǫn nwonyi lo buruju ni akoko ogun ilę wa. Șugbǫn bi ogun ba ti pari, ti ǫtę si bușe, gbogbo rę pari nuni.

Șugbǫn ninu ǫrǫ ișelu ti o dęlę yi, ęgbę Alakukǫ lo kǫkǫ da sunmǫmi silę, ǫrǫ na dabi owe, ęniti o ngbe okiti nișoju ǫbǫ, ǫbǫ dahun wipe, Ha! iran baba-baba on ișę okiti ni nwǫn nșe. Alakukǫ ko nișę meji a yafi bi nwǫn o ti șe da ijǫgbǫn silę ni nwǫn o ma wa. Bi nwǫn ba si fa a de oju rę, nwǫn o poora.

Ko si ęniti o gbiro ijǫgbǫn ni ode Ǫyǫ ri lęhin ti ogun Ijaiye ti pari, ęgbę Alakukǫ lo da silę. Abatęniję ni ęgbę alakukǫ, awǫn tan ǫba Ilaro ti nwǫn fi yǫ kuro ni Oye, awǫn na lo tan Ǫlǫta ti nwǫn fi yǫ ǫ awǫn lo tan Alafin Adedeji ti nwǫn fi yǫ ǫ. Awǫn alakukǫ ko mǫ ișę sunmǫmi gbe ju wa lo bikoșe pe, awa mbęru ofin, șugbǫn awǫn ko będu ofin nitona ni nwǫn ko șe ni oba.

## Ajao Di Balogun Ilu Awe



Ęniti a nwo ninu aworan yi ni Oloye J. A. Ajao ti o ti ję Oye Ǫtun Ǫyǫ, on na ni a gbo wipe Oloye E. A. Laniba, ti o ję Bale ilę Awę ja ewe oye le lori ti o si ję oye Balogun ilu Awę. Nwǫn ja ewe oye na le lori ninu afin Bale na.

Latigba yi ni Oloye J. A. Ajao ti di Ǫtun Ǫyǫ, Balogun Awę.

## Aki Sore Ero K'ayo



Ero nre ile re bi o di jola ni ti alagba Sir Ralph Grey, igbakeji Gomina agba ti ilu Eko ti o ti lo ǫdun męjilelogun nilę Nigeria, o pada lo silu rę A si gbǫ wipe nigbati yio ba tun jade kuro nilu rę, o nlo șe Gomina ilę British Guiana nilę awǫn Wesingisi [...]

A tile gbo wipe ṫ[...] șe odun Keresimasi [...] yi. Iyawo re ko ni te[...] nitori yio se itoju awon [...] won kekere meji lati șe odu[...] nilu won. Lehin odun ni iya[...] wo re na yio lo bo Gomina[...] pelu omo kekere ti o nto l[...] ti oruko re nje Amanda.

## Yi Gbe ...i


LIVE WELL
EAT WELL
eat
"De FACTO"



Kęrę o!

A ni orișirisi ogun German to șęșę de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tirę ki o to tan.

J. A. AJAO
BROTHERS
MEDICINE STORES
7, Egerton Road Lagos



E MA KA
IWE IROHIN
ELETI-OFE
LǪSǪSĘ
O KUN FUN
IROHIN ALADUN


## ǪWǪ ǪLǪPA TĘ AKOWE BANKI

ABĘOKUTA. Ǫmǫkunrin kan ti o nję Samuel Omidiji ti o ję ǫkan ninu awǫn akǫwe National Banki ri, ni awǫn ǫlǫpa ba șe ęjǫ laipę yi ninu kotu ibilę ni Ake. Ęsun ti a gbǫ wipe nwǫn ka mǫ lęsę ni wipe o ngbero lati lǫ fǫ Banki (National Banki) ti o wa ni Ilaro.

Nigbati ǫrǫ yi di mimǫ fun awǫn ǫlǫpa nwǫn fi iwe ipa lǫ yę ile rę wo, ibę ni nwǫn gbe ti ri awǫn irinșę ti awǫn ǫlǫșa fi nfǫle, adajǫ ni ki o lǫ si ęwǫn ǫdun męfa pęlu abǫ.

Awǫn isangbe rę ti ǫwǫ olopa tę pęlu rę ni ǫkunrin Dęręba moto, Michael Eyę, ati Apprentice ti o nję Solomon Jacobs, ni adajǫ gbe ju si ęwǫn ǫdun marun-marun pęlu abǫ. A gbo pe awǫn ęnia nwǫnyi ni awǫn irin ișę titun lǫwǫ ti ęnia le fi fǫle.

## ǪRǪ ǪLǪRǪ KO NPĘ DI TĘNI

Abawun Ajapa joko ni ǫdędę rę ni ǫjǫ kan bęni ǫkunrin kan wǫle de, o ni ha! Ajapa. baba rę ma nku nlǫ. Ajapa dahun pę, bi o ba ję wipe baba lo ku fun ni, eyini ko buru. Baba ęni lo nku funni sin.

Bi nwǫn ti npari ǫrǫ yi tan bęni onișe miran tun de, nwǫn ni ye, ye, ye, Ajapa, iya rę ma nku lǫ Ajapa dahun pe, hǫwu! eyini ko buru, iya ęni na lo nku funni sin.

Laifa ore gun onișe eketa tun de o wipe, ye ye ye ajapa iya iyawo re ma nkulo Ajapa dahun pe hęn - n, oro oloro wa di ti on nikan șoșo wayi. Nitorina ki Ǫlǫrun mașe jęki oro oloro di ti ęni.

Emi ni
Majęnrahun (Alias) Ofę


HINDU SANKARA
Religious Art Jewell...



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawachas. Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

Enclose 4/- Postal order by Air Mail for Catalogues and Literature.

HINDU SANKARA, 431 Archway Road, London, N.6, England

Omo Ilo ELETI - OFE

A-NIJU-WON KO ȘE WI L'EJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28, Kosoko Street, Lagos. "ELETI - ỌFẸ LAGOS"
P. O Box 467 Phone 23370

VOL XI. NO. 652. SATURDAY DEC. 5 - DEC. 11, 1959

# Oruko Awolowo Han Loju Sanma

EKO. Irohin ko to afojuba nilu Eko lọjọ Monday 30th osu November, 1959, nigbati ọkọ ofurufu kekere kan yọ lokere, ti o si bẹrẹ si kọ orukọ Awolọwọ si oju Sanmọ to si tun nya igi ẹpẹti legbẹ. Ibosi Awo, Awo, Awo, gba gbogbo ilu kan ati ọmọde ati agba lo gbe ẹnu soke ti awọn ti nkigbe Awo.

Ẹniti Ọlọrun da, ko ṣe fi ara we, womi na, Awe! jẹki a mu ti ẹgan kuro apara tabi yẹyẹ, Ọlọrun lo yan Oloye Ọbafemi Awolọwọ. Bi a ba si ri ẹniti o ju ni lọ ki agba pe, o ju ẹni lọ, nitoripe, gbogbo nkan ti on ṣe pelu awọn ara ti o nda nwọnyi, jẹ eyiti o ṣe ajeji loju tiwa.

Nitotọ ni Ọgbeni nlanla Herbert Mọkọli, jẹ akọkọ ninu awọn Oṣelu ile Nigeria, ṣugbon ni gasikia, oṣelu iru ti Oloye Awolọwọ ṣowọn. Nigba aiye Ologbe Makọli, on lo mu ilaju nipa oṣelu wọ ilẹ Nigeria. Lẹhinna ni awọn ẹgbẹ oṣelu kekeke dide ti a npe ni Nigerian Youth ti Ologbe Dr. Vaughan jẹ baba ẹgbẹ wọn, lẹhinna ni Dr. Asikiwe bẹrẹ ṣugbọn a ko ri oṣelu kan ti ogboiya ti o ni suru ti ko si ṣarẹ lati ma lọ lati ibi kan de ekeji gẹgẹbi ti Awolọwọ.

Gbogbo awọn nkan ti a nri nigba ọtẹ ti Awolọwọ yi, a ko ri nigba Oṣelu kan ri. Owe kan sọ bayi pe, "Eyiti o ni ogbe, ko ni rere eyiti o ni rere ko ni ogan lẹsẹ, eyiti o ni ogan lẹsẹ' ko le kọ bi akuko".

Ni asiko ti Awolowo ni ẹko ofẹ bẹrẹ nilẹ Nigeria ti awon omode ngba egbogi ni ofẹ, ti moto ko pania ni Idumota mo, moto ngba ona Abẹokuta koja lo si Ibadan ni irowo-rosẹ, nwon nko ilewe nlanla fun awon omo ilewe, awon omo akeko si ngba ẹbun olofẹ lo ko iṣẹ ni ilu Oyinbo. Ọgunlogo ni anfani ti o tun mbo.

E Dibo Fun Action Group.

OMORELA
Is the ever-ready Way to get rapid relief from Cough, Cold, Fever, and all Children ailments.
This is a well tried remedy
a Chemist Product.
Commercial Medicine STORES
LAGOS & IBADAN.



# Nigerian Ports Authority

## INVITATION TO TENDER

Tenders are invited by the Nigerian Ports Authority for the purchase of such scrap materials as the Authority may offer for disposal (with the exception of any items which may be separately offered for sale) during the period 1st January, 1960, to 30th June, 1960, in Apapa Dockyard, Apapa Quays, Customs Quay, or any other particular point where the Authority may have scrap metal for disposal in the Lagos or Apapa areas.

2. Tenders indicating a price per ton should be submitted in sealed envelopes marked "CONFID ENTIAL-TENDER FOR SCRAP" and addressed to the undersigned so as to reach him not later than Saturday, 19th December, 1959. Late tenders will not be considered

3 The successful tenderer will by required to remove, at his own expense, whatever scrap is available for sale with the exception mentioned above) during the six month period indicated, within 7 days of the Authority's notification of such availability and will be required to make the necessary arrangements at his expense for all the scrap removed to be weighed in the presence of a representative of the Authority

4 The Authority do not bind themselves to accept the highest or any tender.

A. R. CORDON
Secretary to the Authority

N.P.A. Notice No. 370
27th November, 1959.



AVAILABLE AT:-
AKOSHILE BROTHERS
5, BALOGUN STREET WEST.
P.O. BOX 599. LAGOS.

STOP YOUR BACKACHE

by quick attention to your KIDNEYS & BLADDER

TAKE DeWitt's Kidney & Bladder Pills

and get rid of the poisons in your body that are the cause of RHEUMATISM JOINT PAINS, BACKACHE and BLADDER TROUBLES




DeWitt's Kidney & Bladder Pills

In a few hours you will SEE results (Urine changes colour)

## Ha! Iya Yi Gbe Bolu Mi Mi

Ọmọ ilewe kan ti o ngba football ṣesi gba bọlu rẹ sinu ọgba oyinbo kan, ṣugbọn ọmọ on bọlu na ko mọ wipe ninu ọgba ni bọlu bọsi, o bẹrẹ si wa titi ko si ri.

Bẹni obinrin aboyun kan ti ara ti pọn dẹdẹ ti o nkanju lọ lati ri Dokita yọ jade ni kọrọ apa ibiti bọlu na bọsi, ọmọ rope nṣe ni iya na gbe bọlu rẹ mi. O bẹrẹ si bẹ aboyun na o nwipe, ẹ jọwọ ma, ẹ jọwọ ma, o si tẹle lẹhin.

Ṣugbọn iya aboyun na ko ṣe akiyesi pe ẹnikan tilẹ mba on wi, adura ki o ṣa tete de ile Dokita ni o ngba. Ọmọ ilewe na bere si sọkun o sa nwi pe, ẹ jọwọ ma, ẹ jọwọ ma.

Ọkunrin kan ti o jẹ ọrẹ baba ọmọ pade rẹ loju ọna ti o nse, ẹ jọwọ ma, ti o si nsọkun, da a duro o bere kilo-jẹ e? Ọmọ na si dahun pe iya ti o nlọ yi lo gbe bọlu mi mi. Ọkunrin na sare siwaju o lo da aboyun na duro wipe Kini nkan ti o gba lọwọ ọmọ yi? Aboyun na duro pelu iyanu, o wipe, ọmọ wo ni, ngbọ! kini mo gba lọwọ rẹ? Ọmọ dahun pe bọlu ni obinrin na dahun pe ha! nibo lo wa, ọmọ na si fọwọ kan ikun aboyun na. ni gbogbo enia ba bu si ẹrin.

## Awon Alagbara meji Foju Kan Ara Won.



Awon enia meji ti a nwo nwonyi ni aṣiwaju awon ijoba alagbara alve meji, Gesi ati Amerika. Ẹniti o duro lowo otun ni Sir Harold Macmillan ti o jẹ Prime Minister tilu Gẹsi, ẹnikeji ni Eisenhower ti iṣe Baba ẹgbẹ ilẹ Amẹrika. Awon mejeji fi oju kan ara won fun oro ajoso.

## KINI ITUMỌ ỌRỌ YI "GBEDE-GBẸYỌ"

OLOTU.

Jọwọ gba mi laye lati dahun si ibere oke yi, Balogun Ogundipẹ ni a gbọ pe o kọkọ sọ ọro yi. lakoko ti Ẹgba ati Dahọmi nja ti nwọn si mu ọkurrin kan leru ninu awon Idahọmi, o nsọrọ ṣugbon ẹnikan ko gbọ ohun ti o nwi, nigbana ni Ogundipẹ wipe tani yio ṣe gbede-gbẹyọ fun wa.

Itumọ gbede-gbeyọ niyi.- ẹniti o gbọ ede ti o si gbọ Ọyọ

Idi rẹ ti a ṣe fi Ọyo kun ni wipe, ni aiye igbani, ile Ọyo ni ogbon pin si. nwon mo ẹdu oro, nwon mo ayinike ede, a tilẹ nso pe "l'Oyo ni ogbon pẹkun si". Ẹni ti o ba gbo ede ijinlẹ Oyo ni a npe ni ologbon.

OLatijo, ki o to di wipe gbogbo enia mo iwe, awon Ẹgba, Ẹgbado, Awori, ati awon Ẹeun, Ẹyo ni nwon npe Ọyo okan ninu orin won so bayi pe:- Igẹrefe jade o, ati ẹyo ati Ẹgba ẹ jade wa woran wa, yẹkọ-yẹkọ, yẹkẹ-yẹkẹ. Nipari oro yi itumo gbede-gbeyo ni, agbede-bi-ara-Oyó, Ẹniti o le yi ede kan pada si ede miran.

Lemomu Ajakuta.

## QWỌ QLỌPA BA AWỌN IGARA-OLE NILU KADUNA

KADUNA. Awon ọlọpa ṣakiyesi wipe awon ọmọ jaguda ati awon ọmọ asunta ṣe ndi pupọ nigboro Kaduna, ti nwon ko ni ibi ti nwon ngbe ni pataki, ayafi ni arin ọja ati ni abẹ ipatẹ. Awon ọlọpa rope bi nwon ba ko awon enia na, ole jija, sobu fifọ, apo titọwọbọ ti o gbojikan larin ilu Kaduna yio dinku nitorina, nwon bẹrẹ si ko awon enia na.

Ọlọpa ko adorin ọmọ osunta nwon ko ọgbon ọmọ jaguda. nwon si ko awon enia mẹdọgbon ninu awon ti nwon pe ara won ni alumongeri ṣugbon ti oju won ko fọ, ti ara won si le, nwon ko gbogbo won lọ siwaju adajọ.

Adajọ wadi won, o si fi suru tọ ẹsẹ ọro won, o so wipe ole ati omo asunta ni gbogbo won. Ohun ti o mu adajo na gba wipe ole ni won niyi:-

(Wo yoku loju ewe keje)

## Itan Oşuogbo

(Apa II)

Lati Owọ Opitan

Bayi ni awọn ọmọ Awo Oşuogbo nşe tobẹ gẹgẹ ti odidi omile-ọlọna fi nsọnu larin ilu. Ọkunrin kan ti o jẹ gbajumo nilu Eko, o ni ọpọlọpọ ọkọ ti o nlọ fi na ọja Ejinrin ti orukọ rẹ njẹ Pinişin, lọsan gangan ọjọ kan ni nwọn wa a ti larin ilu Eko Ọba to wa ni Eko igbani jẹ eyiti o gbona. Bi nwon ba ranşẹ pe enikan pe ki o wa si Iga, afẹku a si ba eluwa re Eyi lohun ti o mu Danmole ko oria bayi pe :-

Aiye lo pa Pinişin (2)
Aiye lo yọda to fi pa Agarawu
Eni ba ti sẹ niga ni nwọn mu lọ pa.
Ti ko modi. Ọpọlọpọ ti ko modi, Laiye ti ran t' Olodumare. Aiye lo pa Pinişin

Nigbati o şe okunrin kan wa ninu awo Oşugbo ti nwon npe oruko rẹ ni Ikuşigbagbe. On gan ni iku ti o pa enia ninu awo Oşugbo on ni Apena won. Nigbati o şe Oluwo won ku, ẹniti o si tun yẹ ki o bo si ipo Oluwo ni Ikuşigbagbe yi şugbon awon omo awo tẹ keta bo nipa bẹ nwon gbe oye Oluwo fun ẹlomiran, eyi ko je didun inu Ikuşigbagbe obinu o si fi ẹgbe sile

Awon omo egbe wa bere si wa ona lati fi pa Ikuşigbagbe nwon şe ode re titi, nwon ko ri mu nigbati o şe awon omo ẹgbe dogungun mo wipe o bu oba, bi o ba si i daa loju wipe on ko bu oba ki o kalo bura loju Oşuogbo. Ikuşigbagbe si gba lati şe be. Nigbati Ikuşigbagbe ma jade nile o mu obe olojumeji o san mo aşọ. Gbogbo won şiko nwon kori si ona Işeri.

Bi nwon ti de ohun bẹni Ikuşigbagbe gbera pa o di şọ ninu omi. Laifa ọrọ gun ẹpọn yọ loju omi, nigbati o şe diẹ si ni Ikuşigbagbe ba yọ lo nwẹ bọ lokere, ni nwọn ba bẹrẹ si kọ orin bayi pe :-

Oşuogbo -o-e (2)
Oşuogbo ẹnikikan
Iwọ Níkuşigbagbe o ẹnikikan

(Koiti pari)

# Igbehin Omo Adanu Meta

Awon omo adanu mẹta lo dẹ iho irẹ, Olori nla, Ọlorun tẹrẹ, ati Onika tẹrẹ gbogbo won lo de iho irẹ. Nigbati nwcn ri iho irẹ kan, nwon ndẹ, nibiti nwon ndẹ iho na, ona di.

Nwon ni ki Onika terc te ika bo iho na boya yio roju iho, bi o ti tẹ ika bo, ponun! ni ika re şe mo inu iho. Olori nla, kigbe Ha! enu re si ya de ipako, Olorun tere ni on nlo so nile, bi o ti fi orun ko owu alantakun, beni orun rẹ re bete. Ẹ o ri igbehin omo adanu meta bi o ti ri.



IRANLỌWỌ FUN AWỌN ONI RỌBA NI AGBEGBE BINI ATI DELTA

Gẹgẹbi ilana Ijọba Iwọ Õrun lati ran awọn àgbẹ ibẹ lọwọ ki nkan ọgbin wọn le dara si, ẹka ti işẹ yi kàn ni Ile Işẹ Àgbẹ ti Ijọba ti bẹrẹ rọba bibà kakiri agbegbe Bini ati Delta, ninu eyiti a o ti ma ri ẽhù rọba ta fun awọn àgbẹ l'owo pọku. Ọkẹ mẹsan abọ ẽhù lo wa ni agbegbe Bini ati Delta.

A ti da awọn ẹgbẹ àgbẹ alasowọpọ silẹ lati jọ mã şe işẹ rọba, a si ti bẹrẹ ẹkọ kakiri awọn agbegbe yi ki awọn àgbẹ ba le ma şe rọba ti o dara ti yio mu owo wa ju eyiti a npe ni "B2" ti nwọn nşe nisiyi.

Awọn oşişẹ Ile Işẹ Àgbẹ si nfun awọn àgbẹ t'o ba fẹ gbin rọba to dara ni imọran l'ọfẹ.

## ỌWỌ ỌLỌPA BA AWON IGARA-OLE NILU KADUNA

O bẹrẹ loju ewe karun

Nigbati awon enia na wa ni timole, nwon towo bo apo ara won, nwon ji ara won ni owo ati siga tobẹ ti o fi di ija ati aso ninu tubu. Adajo ni ki ẹnikokan won lo san ponun kan ati şile kan ki o ma lo, ẹniti ko ba ri owo san, ki o lo si ẹwon ojo mẹnrinla pẹlu iṣẹ aşegan.

Awon olopa so wipe, awon enia na koiti tan, awon nlo ko awon ti o ku.

## ỌWỌ ỌLỌPA BA ONIBARA WỌN

**EKO. Ọkunrin agbalagba kan, ti o ti nfi ọgba ẹwọn ṣe ere jẹ lati igba ewe rẹ wa o dagba titi, sibẹ koiti bọ kuro ninu iwa Ọṣọlẹ, gbogbo ori rẹ pa sinu ọgba ẹwọn, o gba oye Professor ni White College, sibẹ sibẹ 'koiti fi ole jija silẹ. Nrukọ rẹ njẹ Joe Dalẹ.**

**Ohun ti a gbọ wipe ẹni na ṣe ni wipe o ri aye yọ kẹlẹ-kẹlẹ lọ fọ ṣọbu awọn Oyinbo Oniṣowo U T.C. ni ebute Ẹhingbẹti leti Bode laipe yi, o si ko wọn ni ẹru to pọ to Ponun mẹdọgbon le ni ẹgbẹta. Nibiti o gbe fẹ lati ma salọ ni ọwọ ọlọpa gbe ba a.**

**Awọn ọlọpa sọ fun adajo wipe ti ọkunrin na ko le ya wọn lẹnu nitoripe onibara won ni iṣe. Adajo ni ki ọkunrin na Joe Dalẹ lo si ẹwọn ọdun meji, nigbati o ba si pada de lati ọgba ẹwọn ko ma lọ fi oju ri awọn ọlọpa ṣugbọn o ti mbẹ ninu ẹwọn ti o nṣe odun maiun kan tẹlẹ Ha ! agbalagba apẹlẹwon bi obo**


## CARSON PAINTS AND VANISHES












SOLD AGENTS

IKORODU TRADING COMPANY

20, & 28, Balogun Street Lagos.


# Amao Lo Ko Ise Ero nilu Oyinbo



Ẹniti a nwo, ti o jẹ enia dudu ninu aworan yi ni Ọgbẹni kan ara agbegbe Iwọ-Orun ilẹ Nigeria ti o njẹ D. A. O. Amao nigbati o lọ kọ iṣẹ ẹrọ ni Loughborough College of Technology nilu Oyinbo, o nṣe ayẹwo nkan ti Oyinbo ọmo akẹkọ keji ti o njẹ Ọgbẹni M. Bakhuys ara Rooseboom Holland nkọ silẹ. Awọn mejeji na lo duro gbe ara wọn. Ara Holland lo wa lapa ọtun ara ilẹ Nigeria lo wa lapa osi ti o mu ẹrọ dani.

## Bi Ina Ba Njo Ninu Oko, O ni Lati Bowo Fun Ireke.

Niwon ọdun 1899, nigbati awon Oyinbo Gbaçimọlẹ fi nla oju ona Reluwe lo si ilu oke, ko si ọwọ tabi itẹriba lati ọdọ ọmọde si agba, olukuluku enia lo warunki, nwon gbojule orişirişi awon egbogi ti nwon ni lọwọ, nitoripe aiye ti di aiye Olokerake ẹniti o ba ni egbogi lọwọ lakoko na ni a npe ni alagbara. Awon ọmọde a ma dan egbogi wo lara agbalagba, agba ti ko ba si gboju, ọmọde yio pa a ni agbon ẹhin.

O si ṣe ni ọdun 1908, awon igbimọ ilọsiwaju Ẹkọ ṣe orişirişi iwe ti o le kọni gẹgẹbi ọmọde ti ntẹriba fun agba, diẹ ninu awon enia ti a wi nwonyi ni Oloye Ariyọ Şorinolu, J. G. Kuyẹ A. K. Ajişafẹ, Aribiloso ati Şobọ Arobiodu, ati ọpọ enia ti aye ko si lati darukọ.

Orişirişi iwe ni nwon şe. Ninu awon iwe na ni iwe kan ti o nkọ ni bi a ti şe nhuwa (Moral Instruction) gbogbo ile ekọ lo nka iwe na tobẹ ti o fi jẹ wipe gbogbo awon ọmọ ilewe lo mbọwọ fun baba ati iya won ati fun agba pẹlu.

Şugbon ni gẹrẹ ti ogun ajakaiye akọkọ pari tan ti ajakalẹ arun si kasẹ kuro, ti awon alabojuto eto ẹkọ fẹ yi gbogbo nkan pada si ti ọtun, nwon gbagbe lati şe atunşe iwe kekere na (Moral Instruction). Asehinwa asehinbo itiju po-ora, afojudi gb'ode kan.

Iba dara, iba si sunwon bi awon alabojuto eto ẹkọ ba le fi iru imọran rere yi si ero, ki aiye maşe tun pada si aiye Olokerake mọ tabi aiye tani ma mumi. Ki ẹ si ranti pe ọmọde lọgbon, agba mọran ni a fi da ilẹ Ifẹ.

# OWE ILE YORUBA

Ohun t'aja ri, ti o fi ngbo, ko to ohun t'aguntan fi nṣeranwo. Bi ina ba ku afi eru boju, bi Ogede ba ku afi ọmọ rẹ rọpo, ọmọ eni ni ṣehin de'ni. Oju koro, ko npa oju koro jẹ.




## OLOYE OKUNỌWỌ JOYE TI KO RO TẸLẸ

IJẸBU-ODE. Nigbati Oloye Okunọwọ ti o jẹ ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ Action Group fi nsọrọ kakiri nipa idibo ni agbegbe rẹ, o lọ si ilu Okun-Ọwa lati sọrọ ibo nibẹ.

Lairo tẹlẹ, ni nwọn gbe ewe oye de, ti nwọn si fi jẹ oye aṣiwaju fun Okun-Ọwa.

Oloye Okunọwọ jẹ ogunna gbomgbo kan larin awọn Oniṣowo enia dudu ti o mbẹ nilẹ Nigeria, a si gbọ wipe on na gan ni nwọn fẹ dibo fun ni Ijẹbu Central. Oye na yio mọ ori, ade a pe lori, bata a pẹ lẹsẹ.

## OBINRIN KAN NFẸ IBATAN ỌKỌ RẸ

ILESHA. Obinrin kan ti o lọ si idalẹ ba ọkunrin kan pade lati fi ṣe ọkọ. Nigbati o pada wa sile, o lọ jawe ikosilẹ fun ọkọ ti o ti nfẹ ri wipe ki adajọ ba on fi aṣẹ si nitoripe on ti ri ọkọ miran ti on ma fẹ.

Lẹsẹkẹsẹ ni iya ọkọ titun na bo siwaju adajọ o wipe on fẹ fi ye adajọ wipe, o lodi si aṣa iṣẹdalẹ Ijesha wipe ki tẹgbon taburo fẹ obinrin kan na papọ.

Ẹnu ya obinrin na nigbati o gbọ ọrọ yi. Adajo wi fun obinrin ti o pe ẹjọ na wipe se o leti, o si ngbọ bayi bawo lo tiṣe nibati fi ẹgbọn silẹ lọ fẹ aburo. Kele ṣeṣe, ki o lọ wa ọkọ tirẹ ṣiwaju.

## ỌMỌ ỌDUN MẸWA NSAN OWO ORI NI BORNU

(O bẹrẹ loju ewe keji)

omo kekeke na ko fi ni ma sanwo ori mo, nitoripe nwon şi kere pupo.

A gbo wipe nigbati Awolowo fi nsoro ilu kiri ti o de ilu Zinna ti a wi yi, omo ilewe meji lo mu iwe owo ori re ti o gba wa fi han Awolowo. o si şe ileri idera fun won bi on ba wole.

Printed & Published by The Union Printing And Publishing Company 28, Kosoko Street, P.O. Box 467 Lagos Phone 23378